# A BI OGUN SENNAKERIBU ṢUBU

**2 Kronika 32:1-23; 2 Awọn Ọba 19:14-37**

**ẸKỌ 344 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "OLUWA ni imọlẹ mi ati igbala mi; tali emi o bẹ̀ru? OLUWA li agbara ẹmi mi; aiya tali yio fò mi?" (Orin Dafidi 27:1).**

**I Igbogun Sennakeribu ati Igbagbọ́ Hẹsekiah**

1 Sennakeribu dó ti awọn ilu olodi Juda, 2 Kronika 32:1; 2 Awọn Ọba 18:13-16; Isaiah 36:1

2 Hẹsekiah sa gbogbo ipa rẹ̀ lati daabo bo Jerusalẹmu kuro lọwọ ọtá, 2 Kronika 32:2-5

3 Igbagbọ́ rẹ̀ ninu Ọlọrun ràn án lọwọ lati sọ ọrọ ikiyà, 2 Kronika 32:6-8

**II Ọrọ Òdì Sennakeribu ati Adura Hẹsekiah**

1 A sọrọ ẹgan si Hẹsekiah ati si Oluwa, 2 Kronika 32:9-19; Isaiah 36:2-22; 2 Awọn Ọba 18:17-37

2 Sennakeribu kọ iwe ọ̀rọ-òdi ranṣẹ si Hẹsekiah, 2 Kronika 32:17; 2 Awọn Ọba 19:8-13; Isaiah 37:14

3 "Iṣẹ ti adura olododo nṣe li agbara pupọ," Jakọbu 5:16; 2 Awọn Ọba 19:14-19; 2 Kronika 32:20; Isaiah 37:15-20; Orin Dafidi 46:1

**III Idahun Oluwa ati Iparun Sennakeribu**

1 A sọ ti idajọ Sennakeribu lati ẹnu Isaiah, 2 Awọn Ọba 19:20-34; Isaiah 37:21-35

2 Ibẹwo angẹli ti a rán mu ikú wa sori ẹgbẹ́ ogun Assiria, 2 Awọn Ọba 19:35-37; 2 Kronika 32:21-23; Isaiah 37:36

## ALAYE

### Iṣọkan

"Nibiti igbimọ kò si, awọn enia a ṣubu" (Owe 11:14). Lẹsẹkẹsẹ ti Hẹsekiah mọ̀ pe Sennakeribu, ọba Assiria, n bọ̀ lati wa ba oun jà, ó bá awọn ijoye rẹ, ati awọn ọkunrin alagbara rẹ̀ gbimọ̀. Wọn jumọ ṣiṣẹ lati mú odi wọn le, wọn si mura silẹ lati ba Sennakeribu jà. Iṣọkan ti o wà laaarin wọn ni akoko iṣoro yii jẹ́ abayọri imupada isin ti ẹ̀mí ni akoko ijọba Hẹsekiah. Hẹsekiah ṣe ohun ti o le ṣe nigba naa, o si "sọ̀rọ iyanju" fun awọn eniyan rẹ.

### Imulọkanle

"Ẹ mu ara le, ki ẹ si ṣe onigboiya, ẹ má bẹ̀ru, bẹ̃ni ki aiya ki o má ṣe fò nyin" (2 Kronika 32:7). Igba meloo ni iru ọrọ iṣiri bayii ti rú ọkàn awọn ọmọ-ogun Kristi soke lati tẹ̀ siwaju ninu ija igbagbọ́. O le jẹ́ ipin awọn ọmọ-ogun Rẹ̀ lati la afonifoji ojiji ikú kọja, ṣugbọn ọmọ Ọlọrun kò gbọdọ bẹ̀ru, nitori ti o le gbé oju rẹ̀ soke Ọrun pẹlu igbagbọ́ pe Ọlọrun yoo "pa a mọ li alafia pipé, ọkàn ẹniti o simi le ọ" (Isaiah 26:3).

### Ogun Ọlọrun

"Awọn ti o pẹlu wa jù awọn ti o pẹlu rẹ̀ lọ" (2 Kronika 32:7). Ọba Assiria ni ọmọ-ogun ti o lọ ṣua; o tilẹ gboju-gboya lati fi ẹgbaa ẹṣin lọ Hẹsekiah ki ẹgbẹ ogun tọ̀tún tosì ba le fẹrẹ dọgba, sibẹ Hesekiah le wi pe "Awọn ti o pẹlu wa jù awọn ti o pẹlu rẹ̀ lọ." Bi o tilẹ jẹ pe oju rẹ̀ kò ri awọn ẹlẹṣin ati awọn kẹkẹ iná ti o yi i ká gẹgẹ bi o ti ri fun iranṣẹ Eliṣa, sibẹ gẹgẹ bi Eliṣa o mọ̀ pé wọn wà nibẹ.

Nigba pupọ ni a ma n gbọ́ riru omi okun, ti a si n gbọ̀n pẹ̀pẹ, lai ranti Ẹni ti o wi pe "Nihin yi ni iwọ o dé, ki o má si rekọja, nihin yi si ni igberaga riru omi rẹ yio gbe duro mọ" (Jobu 38:11). O yẹ ki o da wa loju pe, "Nigbati ọta yio de bi kikún omi, Ẹmi Oluwa yio gbe ọpágun soke si i" (Isaiah 59:19). Bi ikun omi tilẹ wó ogiri alagbara, ti o si wó adamọdi ile ti a fi ipilẹ rẹ̀ sọlẹ sori iyanrin, sibẹ ọpagun Oluwa yoo duro gbọnin ninu iji lile, bẹẹ ni igbi omi ti o rọlu u ki yoo le bi i wó.

Bi apa ẹran ara tilẹ lagbara, ta ni o tobi ju, ẹdá ni, tabi Ẹlẹda ti o da a? Bi Ẹlẹda ba le fi ọrọ ẹnu Rẹ da a, kò ha le fi ọrọ ẹnu rẹ kan naa gba ẹmi rẹ̀. Njẹ o yẹ ki awa ẹdá ọwọ Rẹ̀ ki o maa bẹru lati jọwọ ara wa yii lọwọ fun Ọlọrun nigba idanwo ati ipọnju, ni ero pe apa ẹran-ara lagbara ju Ọrọ agbára

Rẹ̀? Njẹ o yẹ ki a maa gbọn jinnijinni nigba ti èṣu ba n bu ramuramu nigba ti a mọ pe oun kò le ṣe ju bi Oluwa ti gba a laye lọ? Ọlọrun wi pe, "Emi kò jẹ fi ọ silẹ, bẹni emi kò jẹ kọ ọ silẹ" (Heberu 13:5).

**Ifisùn**

"Awọn enia na si gbẹkẹ wọn le ọ̀rọ Hẹsekiah, ọba Juda." Wo bi ọtá ti n sọrọ èebú! Wo bi o ti n sọrọ ẹgàn nigba ti o ri bi awọn eniyan naa ti gbẹkẹ le Ọlọrun! Iwọ ha gbọ́ bi o ti n wi pe "Iwọ n fi iku ṣire bi o kò ba ro nnkan ṣe! Ebi ni yoo pa ọ kú! Oungbẹ ni yoo gbẹ ọ pa! Ọlọrun ti kọ Hẹsekiah silẹ wayii, Ọlọrun ti binu si i! Wo gbogbo ile oriṣa ti Hẹsekiah ti wó lulẹ ati awọn pẹpẹ ti o ti parun!" Nigba pupọ ọtá a maa tọka si agabagebe bi ẹni pe Onigbagbọ́ tootọ ni oun i ṣe. Lotitọ Hesekiah wó ibi giga lulẹ, ṣugbọn o ṣe e gẹgẹ bi ilana Ọlọrun. Leke gbogbo irunu rẹ̀, Sennakeribu sọrọ odi ni ti pe o sọ wi pe Oluwa wà ni iha oun ati pe Oluwa ti wi fun oun pe, "Gòke lọ si ilẹ yi, ki o si pa a run" (2 Awọn Ọba 18:25).

**Idakẹ Jẹẹ**

"Ṣugbọn awọn enia pa ẹnu wọn mọ́, nwọn kò si da a li ohun ọ̀rọ kan: nitori aṣẹ ọba ni, pe, Ẹ máṣe da a li ohùn" (2 Awọn Ọba 18:36). Kò ṣe anfaani lati maa bá eṣu jiyan. Kò ṣanfaani lati da a lohùn. Ninu gbogbo ẹsun ti a fi sun Un, Jesu kò dá a ni "gbolohun kan" (Matteu 27:14); Mikaẹli, olori angẹli, dá Satani lohùn pe, "Oluwa ni yio ba ọ wi" (Juda 9). Lati maa ba awọn ti o lodi si ijẹwọ igbagbọ́ rẹ jiyan kò le mú ohun rere kan wá. Ta kete si ijiyan ati gbolohun asọ̀, ṣugbọn, "Ki ẹ si mura tan nigbagbogbo lati dá olukuluku lohùn ti mbere ireti ti o mbẹ ninu yin, ṣugbọn pẹlu ọkàn tutù ati ibẹru" (1 Peteru 3:15).

**Adura Hesekiah**

Nigba iṣoro, Hẹsekiah rẹ ara rẹ̀ silẹ, o fa aṣọ rẹ̀ ya, o fi aṣọ ọfọ bora, o si lọ si ile Oluwa. O ranṣẹ si Isaiah, wolii alagbara ninu Ọlọrun nì, lati so ọwọ pọ̀ pẹlu rẹ̀ ninu adura. O ba awọn eniyan mimọ́ wọnyii ninu jẹ́ lati gbọ́ bi awọn alaiwa-bi-Ọlọrun ti n sọrọ odi si Ọlọrun Israẹli, ti wọn si ka A si bi ọkan ninu awọn ọlọrun keferi ti i ṣe iṣẹ ọwọ awọn ẹlẹṣẹ. Bi Hẹsekiah ti tẹ́ iwe ẹ̀gan ti Sennakeribu kọ si i siwaju rẹ̀, o bẹ Ọlọrun lati daabo bo Jerusalẹmu "ki gbogbo ilẹ ọba aiye le mọ̀ pe iwọ OLUWA, iwọ li Ọlọrun nikanṣoṣo" (2 Awọn Ọba 19:19).

**Idahun**

Ọlọrun ranṣẹ pada si Hẹsekiah pe Oun ti gbọ́ adura rẹ̀, O si jẹ ki o mọ eredi rẹ̀ ti Sennakeribu fi le ṣẹgun awọn orilẹ-ède wọnni. Agbara rẹ̀ kò jọ ni loju mọ́ nigba ti Oluwa fi hàn pe awọn orilẹ-ède ti o parun dabi "ọkà ti o rẹ̀ danù ki o to dàgba soke" (2 Awọn Ọba 19:26). Oluwa ti fi hàn niye igba pe Oun ni alakoso ni ijọba awọn eniyan. Farao ọlọ́kàn lile kọju ija si Ọlọrun titi Ọlọrun fi pa Egipti run. Nebukadnessari gbé ara rẹ̀ ga titi Ọlọrun fi lé e jade kuro ni ijọba rẹ̀, ti o si pa iye rẹ̀ dà. Bẹlṣassari n mookùn ninu ẹ̀ṣẹ titi ọwọ́ Ọlọrun fi kọ iparun rẹ̀ sara ogiri. Jẹ ki Sennakeribu ati gbogbo awọn ti n jọba ni ilẹ ayé mọ̀ pe "Kò si aṣẹ kan, bikoṣe lati ọdọ Ọlọrun wá: awọn alaṣẹ ti o si wà, lati ọdọ Ọlọrun li a ti làna rẹ̀ wá" (Romu 13:1). Eṣu kò le lọ tayọ ibi ti Ọlọrun ba gba a laye dé. Kẹ́kẹ pa mọ́ Sennakeribu lẹnu o si pada si ilu rẹ̀ pẹlu itiju.

**Angẹli Apanirun**

Akewi Ọlọla Bryon kọ ọrọ arofọ ti o gbadun nipa bi Ọlọrun ṣe rán angẹli Rẹ̀ ti o pa ọkẹ mẹsan-an le ẹgbẹẹdọgbọn eniyan ati gbogbo awọn alagbara ogun, ati awọn aṣaaju ati awọn balogun ninu awọn ogun Siria.

<u>**IPARUN SENNAKERIBU**</u>

**Awọn Assiria sọkalẹ bi ikookò ti i bẹ́ sinu agbo,**

**Awọn ọmọ-ogun rẹ̀ n kọ mọnà ninu aṣọ elese aluko**

**ati wura;**

**Ọkọ̀ wọn si n kọ mọnà bi itanṣan irawọ lori okun,**

**Nigba ti igbi omi okun ba n fẹ́ lẹlẹ ni àṣaalẹ́ lori okun Galili.**

**Gẹgẹ bi ewe igi igbẹ ti i tutu yọyọ ni igba òjò,**

**Bẹẹ ni a ri awọn ọmọ-ogun wọn ni àṣaalẹ́ pẹlu ọpagun wọn;**

**Gẹgẹ bi ewe igi igbẹ ti i rẹ̀ danu lakoko ẹẹrun,**
**Bẹẹ ni a ri awọn ọmọ-ogun wọn lọjọ keji ti wọn ti ṣubu**
**lulẹ lọ bẹẹrẹ bẹ.**

**Nitori pe Angẹli Apanirun ti fò kọja,**
**O si mi eemi rẹ̀ si oju awọn ọtá bi o ti n kọja lọ;**
**Oju awọn oloorun wọnyi si di tutu bi yinyin,**
**Wọn mí kanlẹ lẹẹkan, akukọ si kọ lẹyin ọkunrin!**

**Awọn ẹṣin ṣubu yakata, imú wọn si fẹ̀ gan an**
**Wọn kò le fi imu wọn mi eemí igberaga mọ́:**
**Ifoofoo ẹnu wọn funfun lọ saa lori ilẹ,**
**O si tutu bi imú ajá.**

**Ẹlẹṣin ṣubu lulẹ gbalaja, àgbọn isalẹ ti yẹ̀,**
**Iri sẹ si i lori, ẹwu irin si dipẹta;**
**Gbogbo agọ parọrọ, oluṣọ kò si fun ọpagun,**
**A kò r'ẹni gbe'dà, ohun ipè dẹkun.**

**Awọn opó Aṣuri pohunrere ẹkun kikan,**
**A si fọ́ gbogbo oriṣa ninu tẹmpili Baali;**
**Agbara keferi, ti a kò gbọwọ ida soke si,**
**Ti yọ́ bi yinyin niwaju Oluwa!**

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni Hẹsekiah ṣe lati daabo bo Jerusalẹmu?
2 Ki ni ṣe ti Hẹsekiah fi le wi pe "awọn ti o pẹlu wa jù awọn ti o pẹlu rẹ̀ lọ"?
3 Iru iha wo ni awọn eniyan naa kọ si ọrọ Hẹsekiah?
4 Sọ oriṣiriṣi ọna ti Sennakeribu fi ṣe aṣiṣe nigba ti o fi ẹsun sun Hẹsekiah ati Ọlọrun.
5 Ki ni ṣe ti ọba Assiria fi le ṣẹgun ọpọlọpọ orilẹ-ède?
6 Ta ni Hẹsekiah ke si lati ba a gbadura?
7 Nitori ta ni Ọlọrun fi wi pe Oun yoo daabo bo Jerusalẹmu?
8 Awọn meloo ni angẹli Oluwa pa?
9 Iru ipo wo ni awọn ti a pa naa wà laaarin ogun?
10 Ki ni ṣẹlẹ si Sennakeribu?